# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 713 SATURDAY, JUNE 6, 1964 (2D)


## Ẹnikan Yin Aṣoju Ijọba Ni'bọn!

STOCKHOLM-: jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati Aṣoju Ijọba Ethiopia, ọ gbẹ ni Abate Agede, ẹni ọdun mọkandinlogoji pẹ jade ninu ile rẹ ti ẹnikan si yinn ni ila ni agbedu ikau ni ọjọ ọjọ Bo ti iṣe ọjọ kẹan oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe Ọgbẹni Agede ni Asojn Ijọba Ethiopia ninu ilu Stockholm o si ti de inu ilu na to ọdun dlẹ na pẹlu iyawo rẹ pẹlu ọmọ wọn mẹta.

Ṣugbọn bi o ti ṣe fẹ jade ninu ile ni ọkanrin kan ba yin in nibọn ni ọjọ na Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ọmọ ilu na ti nwọn nṣiṣẹ ninu ile Aṣoju Ijọba na ba sale jada ti nwọn si gbe Ọgbẹni Agede ninu agbara ẹjẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn sare de ti uwọn si gbe lọ si ile iwosan Agbọ pe awọn Do kita tise iṣe abẹ fun ọta ibọn marun ni nwọn ri yọ ninu ikun rẹ. Ọkunrin-na wa ni agbedemeji aiye on orun ni ile iwosan na nisisiyi

Awọn ọlọpa ti mu 'ọkunrin na nitori ọran na awọn ọlọpa si tun wadi ọrau na lọwọ Ki ọlọrun ṭete fun Aṣoju ijọba na ni alafia O.

# ILE IGBIMỌ APAPỌ IJỌBA FẸ ṢE IPADE PAJAWIRI

EKO:— Ni deede agogo meji ọsan ana ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni irohin kan wa pe, Oloye Adeniran Ogunsanya, ọkan ninu Olori ẹgbẹ Alakukọ ninu ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria kesi Apapọ Ijọba Naijiria ati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa pe, ki o yara tete pe Ipade, ki awọn ọmọ Ile Igbimọ o le jiroro lori eto ti Ijọba yio ṣe ki awọn oṣiṣẹ le pada si ẹnu iṣẹ wọn.



Oloye J. M. Johnson
Minista Alamojuto Eto Iṣe

Irohin fi ye wa pe Oloye na ti kọwe ranṣẹ si Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria pe, ki o tete pe ipade Ile Igbimọ na.

Oloye na tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, o yẹ ki Apapọ Ijọba tun ipinnu wọn ro daada lori ọran awọn Igbimọ oluwadi Ẹkunwo oṣu Morgan ati ọran awọn oṣiṣẹ.

Ọgbẹni James Otobo lo kọkọ kọwe si Alhaji Balewa ẹniti o wa ninu isimi ọsẹ mẹfa lọwọ bayi ni ilu rẹ Banchi pe ki o tete ma a bọ lati ṣe ayẹwo ọran awọn oṣiṣẹ ti nwọn da iṣẹ silẹ.

Oni rohin wa kan ran wa leti pe, oni l o d i ọjọ k ẹ f a ti awọn oṣiṣẹ ti da iṣẹ silẹ ni Naijiria ti nwọn ko fi ọwọ kan iṣẹ kankan ṣe.

A gbọ wipe Igbimọ oluwadi ẹknuwo oṣu sọ pe, ki Ijọba fi pọnún mẹta kun owo awọn oṣiṣẹ ni oṣu, ki Ijọba si san owo ọya-oṣu mẹsan fun awọn oṣiṣẹ.

Ṣugbọn Apapọ Ijọba sọ pe awọn ko le fi kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ ju pọun kan abọ lọ. Bakanna ni Ijọba sọ pe, awọn ko le san owo-ọya a w ọ n o ṣ u mesan, ṣugbọn o ṣ u meji pere ni awọn le san.

Lati ọjọ na ni awọn oṣiṣẹ ti taku mọ Ijọba lọwọ, ti nwọn si fi aake kori p e, awọn ko ni ṣiṣẹ.

Nitori iṣẹ ti awọn oṣiṣẹ da silẹ yi, gbogbo nkan ti bẹrẹsi jagọ kakiri gbogbo ilu

Awọn ara ilu ko ri omi pọn larin ilu to bi ' nwọn ti nri omi pọn lati ẹhin wa

Awọn oṣiṣẹ ina mana-mana pa ina ni owurọ ana eyi si fẹrẹ jẹki iwe wa o pẹ lati tete jade ni owurọ yi nitoripe a ko ri ina tẹ iwe wa.

Lẹhin nkan bi wakati mẹfa ni a to le ri ina lo ni ana, adupẹ pe awon alaṣẹ na fun wa ni ina, a si tun dupẹ pe iwe na jade

Nitori gbogbo nkan ti ko lọ dede yi awọn Alaṣẹ Ile iṣẹ Minista Alamojuto eto iṣẹfun Apapọ Ijọba Naijiria ti kesi awọn Asiwaju ẹgbẹ



Alhaji Abubakar
Alakoso Apapọ Ijọba

osisẹ pe awọn fẹ ba wọn sọrọ ni owurọ yi ninu ile iṣẹ wọn.

A gbọ wipe awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn osisẹ na ti gba iwe iṭe na nwọn si gba lati lọ ba awọn Alaṣẹ ile iṣẹ Minista na sọrẹ loni.

Irohin fi ye wa pe ni dede agogo mejila owurọ yi ni ipade na yio bẹrẹ. A sile

WO OJU EWE KẸFA

## AGOGORO EYỌ !

EKO:— Lati bi ọjọ mẹta ni awa oniwe Irohin Imọlẹ ti nsọ fun gbogbo ẹnyin ara ilu pe, oni ni awọn ara Eko fẹ se are ẹyọ Adamuoriṣa ni Igboro ilu Eko.

Awọn alapata ti ṣe ikede fun gbogbo enia pe ko ni si ẹran lọja ni oni nitori are agogoro ẹyọ ti nwọn yio ṣẹ loni,

Awa oniwe irohin Imọlẹ kesi gbogbo enyin ara ilu pe ki ẹ ma ṣe wọ bata tabi de fila pade ẹyọ loju ọna

Bakanna ni a si tun kesi ẹnyin obi ki ẹtọju awọn ọmọ nyin daada loni.

## Rogbodiyan Bẹsilẹ Ninu Mọsalaṣi!

Eko:- gbogbo enia bẹrẹsi sare ọlọmọgbọmọpọn nigbati awọn enia ti o o wa ni adugbo ri bi awọn enia ti ṣe nsare jade ninu Mọsalaṣi Alalukurani ti o wa ni opopo Arọlọya Eko ni deede agogo meji ọsan ana ọjọ ẹ ti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe ede-aiyede kan lo wa larin awọn Alagba meji larin Ijọ Ọlọrun na lori ọran owo kan ti awọn ọmọ Ijọ na nda ninu Mọsalasi na.

Nigbati Ija na bẹrẹ, gbo-gbo awọn ọmọ Ijọ ti nwọn fẹ kirun Jimọh ni nwọn ko ri aye kirun, Awọn enia diẹ ninu wọn si tun dide lati pari rẹ fun wọn.

Ṣugbọn nigbati ọrọ na fẹ di gidigbo ninu Mọsalaṣi, ni awọn Janmaa ba bẹrẹ si fo oju ferese jade ti gbogbo Maṣalaṣi na si t ka ni deede agogo meji ọsan

Oniwe irohin wa Ejo-ngbọro yio wadi ọrọ na lati mọ ohunti o da ija silẹ, bi o ba si ti wadi ọrau na si, ẹ o ma a gbọ ninu iwe Irohin ọsẹ ti mbọ.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 15)

**Lati Ọwọ J. O. Shoyinka**

Iwin iroko jẹ alatako ni ipade nla yi, o ni on fẹ mọ iye ti awọn ni lọwọ Iye awọn ọmọ enia ti, Sọnpọnna pa ati idi rẹ to fi pa wọn. Iye enia ti Ogun pa, ati idi rẹ ti o fi pa wọn, idi rẹ ti awọn Iwin ki ifi jẹki awọn ọdẹ ṣọdẹ ninu igbo loru.

On si tun dan nimọnran pe ki awọn igbimọ fi eri-kori, ki wọn yọ Eṣu kero ninu ẹgbẹ yi nitoripe iwa to nhu nile aiye kodara atipe on lo nda irokerudo silẹ nile aiye. Nigbati Eṣu gbọ, oroju korokoro bi ẹranko to gbọgbẹ, o fẹ sọrọ, ṣugbọn Sọnpọnna kilọ fun un pe ki o farabalẹ, o si gba bẹẹ. O ya gbogbo ipade lẹnu toripe kigbọ-kigba ni Eṣu.

Iwin Iroko tun bere ohun ti nwọn ofi ṣe ajọyọ o ni ki oto sọ bayi tan ogun da hun pe enia abirun lori ni a o fi ṣe e.

Awọn enia abirun lori ti o nwi yi ni ogbo ulẹogun ati awọn ẹgbọn rẹ nitoripe nwọn ti wa ni tubu (prison cell) ogun lati ọjọ jọjọ ibọ ẹbiti ni o nbọ wọn ki wọn le lọra fun pipa-jẹ Ayọrọnbọ f'eti ko, o wo kọrọ, o dakẹ bi ẹnipe ko gbọ ohun ti Ogun sọ.

Bi Sọnpọnna ti dide ariwo ta ye e? Nwọn bẹrẹ si patẹwọ po-po-po, o ni idahun ekinni si Ibere Iwin Iroko ti pe owo ti ẹgbẹ ri jẹ ọtalenirugba pọnnu, gbogbo wọn rẹrin muṣẹ. Ibere keji nio kan Sọnpọnn gbọn gbọn gbọn, o ni ọgọrọ enia l'on npa lọdọ-ọdun ni pa aipikita, o ni lọdọ-ọdun ni on ma a nparada di ọmọ enia, on a si wa si ile aiya lati wa kilọ fun wọn pe on ko fẹ ilu. Ijo ati ife sisu lọsan gangan, ṣugbọn sibẹ sibẹ kigbọ-kigba l'ọmọ araiye jẹ, gbogbo ohun ti mo kọ yi, ni nwọn ma nṣe nitori idi eyi ni emi nṣe ngma a ba wọn ja.

Idahun si ibere kẹta ni pe a ki ti oju ẹlẹsẹ mẹsan ka a, nitoripe ọgbẹni Ogun wa nihin, ṣugbọn gẹgẹbi ẹ ti yan mi lati dahun awọn ibere wọnyi ngo dahun rẹ laipẹ Ogun sita lọrọ kan emi ati Ogun ti ṣe ọmọde ri, ki i mu emi afẹjẹ, af'ẹmu. Airimu rara emu, laiko pa enia tabi aja (ẹran-Ogun) ko le ri ẹjẹ mu, abọ mi re o, ara, enia ti ogun si npa lọdọdun ko ni ye.

Bi o ti sọrọ tan, Ogun fẹ ọhin, o rẹrin muṣẹn, ehin rẹ pọn wẹ ẹ fun ẹjẹ mimu, ko si eda alaye ti o le woo, a fi awọn ẹbọra bi tirẹ.

Idahun si ibere kerin yi ṣoro pupọ fun Sọnpọnna lati dahun, toripe ọrọ na kan Alaga, Iwin Iroko bi o tilẹ jẹ on lo bere ọrọ na O dakẹ si i, ati dahun ibere na disọ bẹni Iwin Iroko



Eemọ re e! Ẹlẹsẹ kan!!

tọrọ gafara lati dahun ibere na, nwọn si gba fun un.

Oni lati igba Iwaṣẹ, eni abirun lori ni awọn iwin awọn enia ẹgbẹ nwọn na lo sọ wọn d'ẹni igbo, eni odo ati ẹniti ofi ibugbe rẹ ṣe inu iho igi. Ọsan wa fun ririn kiri ọmọ enia lati maa wa ohun jijẹ. Oru si wa fun awọn Iwin oke ati odo lati maa rin kiri fun atijẹ, ati mu Ibinu si ni fun alaye lati tun maa da wọn l'amu, idi rẹ ti Iwin fii ngma a le awọn ọdẹ ni ale ja leti ni yi

Gbogbo nwọn patẹwọ fun Alaga o si joko.

Imọran karun yi ja Sọnpọnna laiya lati fi siwaju Igbimọ fun didaro. Ko ṣe e ṣe toripe Eṣu paapa duro gangan lati gbọ ẹniti yio daruko on, ọrọ di wo mi ngwo ọ.

Ogun dide, o ni on faramọ imọran Iwin Iroko pe ki nwọn yọ eṣu lẹgbẹ, gbogbo nwọn pa lọlọ, ẹnikẹni ko sọrọ, inu bi o gun laka iye. oni ẹnyin ojo buruku yi, mo ṣebi Ọlọrun to da Eṣu lo da nyin.

Lẹhin iku sare ni, ẹ ha ti ṣe le ma a bẹru ẹniti o le pa ni ti ko si le ji ni.

Emi Ogun awo, ko bẹru ẹnikan gbangba l'aṣa nla, Eṣu paapa ti mọ pe agbara mi ju ti on lọ, ti mo ba binu nisisiyi o di pẹ e ntuka. Eṣu paapa ko le duro. ere a sa lọwọ lati ni...

Ayọrunbọ f'eti ko nwọn leti on ni Eṣu ṣoro le, o si ṣoro yọ lẹgbẹ, ohun ti awọn le ṣe ni pe, ki awọn le ṣe ni pe, ki awọn ma a fi orin iyin, yin Oluwa Ọba Eleda. Nwọn bẹrẹ Eṣu ko dagbere ti o fi sa a lọ nitoripe ki fẹ gbọ ọrọ Ọlọrun ati igbayi ni Ayọrunbọ ti ti ọgbọn ati lakaye yọ eṣu lẹgbẹ.

Ọjọ buburu Eṣu gbomi wẹ, awọn ọmọ Onilogbo niagun sẹnkẹn, nitoripe ọjọ iku pe, nwọn ṣa wọn s'orun ki ogun ba le ma a jade dada lara wọn, nwọn si npọn wọn lara la.

Nwọn ko le ja rara nitoripe, ati di wọn lọwọ, di wọn lẹsẹ, ipa pin. Bi alapata ti nfẹ da ọbẹ le wọn lorun, ni Ogbojuleogun bẹrẹ si ke li ohun rara pe Ayunọrunbọ o nwo wa ni? Idamu de ba wa, gba wa o Iku oro de.

Ki oto wi bayi tan Ayọrunbọ dide okilọ fun alapata na pe ki o ma da ọbẹ le awọn ọmọ Onilogbo lọrun o si dawọ duro.

Inu bi wọn tobẹ gẹ e, lọ gan nwọn panu pọ lati yọ Ayunọrunbọ ni Alaga wọn si ṣe bẹ ẹ wọn wa fi ṣonpon na ṣe alaga ṣọnpọnna ti o ti fẹ ẹ ẹran enia tẹ! yẹ ara fi ọwọ si i pe ki apa wọn ni kiamosa

Oni lati igba ati ti ṣe ipa de ẹkan gbọ ohun mi ni ẹ ko mọ mi nisiyi ngo fi ara mi han nyin emi ni Ayọnọrunbọ ẹiyẹ buburu ti nje lawujọ aje emi ju ẹnikẹni lọ ninu aiye Ọba ti nko ba si lẹhin rẹ awọn ilu ko ni pẹ



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

yọ loye oni segun ti nko ba l'owo sọya funbi onwo igba alaisan pọbọ ni yio ma jau si nitoripa gbogbo ọrọ ti ẹ sọ nipa awọnọmọ onilogbo ko bo sii iren ori wọn ko gbọdọ yẹngẹn

Gẹgẹbi alaga ipade yi, ẹ tun wọn sile ki wọn ma lọ ni alafia ki se pe mo da u imọran mọ pa lasẹ ni.

Nwọn bẹrẹ si kun hun un bi ejo inu koto Ẹnikẹni o le fesi si ọrọ Ayọrunbọ nitoripe oba wọn lojiji ka na ni ogunlakaiye dide, oni ẹnyin enia mi o eti yin melo nwọn ni meji ẹ gbọ ohun ti alaga wi abi ẹko gbọ wọn ni awọn gbọ o tun bere pe ewo ni sise ni pa ọrọ awọn ọmọ Onilogbo nwọn ni pipa jẹ ni wọn.

**For Sale**

Jeep Land Rover with Good Condition
Apply to:—

**Mr. Adeniji**
16, Bamgboṣe Street, Lagos

# Nję Adura Nsọ Ọkeişoro Di Pętęlę ?

## Lati Ọwọ ỌMỌ OLUGBALA

Mọ ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ nlẹ mbẹ hun, ẹ si ka atijẹ, ati mu yi. Oluwa ki o wa pẹlu wa, Jesu yio gbadura onikaluku wa.

O fẹrẹ jẹ pe gbogbo igba ni awọn enia miran ti o jẹ alaiko gba ara wọn gbọ ma bere ibere yi pe nję adura a ma şẹ ti ? Şugbọn gbogbo awọn ti o nsọ eyi jẹ alaiko ni igbagbọ.

Lati o ni lọ mọ ti mura lati ma fun yin ni ọrọişiri ni pa Ọlọrun papa nipa ebayọri adura, eyiti ngo bẹrẹ loni ni torina mo gbagbogbo ẹnyin ọmọ Olugbala ni yanju lati ma ka Irohin-imọlẹ lojoju mọ.

Ko si akoko lati gbadura ko si akoko lati ba Ọlọrun sọrọ' Iwọ nja Ọlọrun lo'le" "enia yio wa ha ja Ọlọrun ni ole" Eyi ki nşe ọrọ owo nikan, adura, ifẹ ati işẹ isin pẹlu. Bakanna ni akoko rẹ lati fun Ọlọrun.

Awọn enia ti ko ngbadura şe alenu ohun gbogbo ti o le fi sin Ọlọrun, Oluwa fẹ ki a jẹ enia ti ngba dura ki a si di iwo pẹpẹ mu ti ao fi gbadura yọri.

Nigbati Jakọbu ti ru ẹbi ati ohun ini rẹ şẹhin odo, o ba Ọlọrun jijakadi o si bori titi di afẹmọjumọ adura rẹ lọ tarata si ọrun rekọja awọn irawọ. O si kan itẹ Ọlọrun padabọ silẹ.

Angẹli na iba ti fi silẹ, şugbọn o wipe "Emi ki yio jẹki iwọ kio jẹki iwọ kio lọ biko şe pe iwọ ba sure fun mi" Angẹli na si wipe, 'Iwọ ti ba Ọlọrun ati enia ja iwọ si bori" Genesisi (32 26 28)

Iwọ ha ti ja ijakadi ni gbobgo oru, enia bawọnyi ni Ọlọrun nfẹ bukun ti osi nfẹ tu ẹmi rẹ le lori, awọn enia ti yio bori ati pe lẹhin ti wọn ti jijakadi ti wọn si bori nwọn kiyi o jẹki olubukun na lo titi wọn yio fi gba esi.

Ọlọrun bu ọla fun adura, o sibu ọla fun awọn enia ti o ngbadura nigbati nwọn ba si gba agbajumọ ọrun si silẹ nwọn o si ri ibukun gba.

Nibiyi ni ngo duro ni ọsẹ yi na şugbọn ti Jesu Kirist ko kọ fun ọmọ rẹ ti o mbọ ngo tun ma ba ọrọ mi lọ lori adura ọ ku işẹ o.


## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu bun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọfi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ şe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni P O R A L ojulowo hanunhahun, atamatase egbogi fun, Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile. Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone:- 2278 (Ọj, Ita Faji)
8, Palmchurch Street, Lagos Nigeria
ADEDUN CHEMISIS
4, WAKE MANSTREET, YABA



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tab şẹ şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa la ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de ,adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun pata pata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Şọbu:a

Waterool Medicine Store
8, Palm Church Street, Lago-
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba



## "Figurana"

Jẹ ojulowo egbogi ti awọn Jamani şẹşẹ şe iwadimi fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba ,TOBI' ju lati ri mu ki nwọn le fi jọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio ma a jẹ rara, bẹ sini ko lewu ni li o fun enia rara, yala Ọkunrin tabi Obinrin.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupoju, ki nşe ohun ti o dara rara, ọpọlọpọ amodi ni onko ba, enia bi Lakuregbe, Aiko le gbera nilẹ bi o ba joko Aiya lile kiki tabi jija nigbana, Aiko le mi kan lẹ daradara Ara wiwo, tabi wiwuwo, Emi mimi họ-họ ti orişirişi amọdi miran pẹlu.

Şa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ y'o ri ayipada ati alafia yio desi Bere ni Şọbu awọn Elegbogi Jamani ni igboro ilu Eko.

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba
ADEDUN CHEMISTS'
14, WAKEMAN STREET' YABA,


## E Ma Polowo Ọja Nyin Sinu Iwe IrohinImọlẹ

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin o

Ẹ ku awurọ o, gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ gbogbo yin ni mo ki laidaenikan si o. Inu mi dun lati sọ fun yin pe, Ibadan ni ile O'uyọle nibiti ole gbe njare onirkan ni mo wa nisisiyi gẹgẹbi ọrọ asọtẹlẹ mi ẹ o ma ka nipa awọn iriri mi ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

Alafia ati ayọ ni ao fi pade ara wa o Aṣẹ.

Awọn eyi-jẹ-epi-o jẹ niwaju "Lagos University Teaching Hospital."

Bi mo ti nke si awọn Ọlọpa to nipa awọn eyi jẹ eyi o jẹ, sibẹsibẹ nko ri kọrọ kan lati ọdọ wọn eyiti awọn oni jibiti na iba fi parẹ, uṣe ni nwọn npe e si i.

ITIJU

Itiju nlanla ni o jẹ fun awa ara Eko lati ri i pe l'ẹgbẹ.

Lagos UniversityTeachin Hospital gangan ni awọn onjibiti na ti nte tẹtẹ laisi idagiri awọn ọlọpa Eyi ko bojumu rara o nitori idi eyi iba dara pupọ ti awọn ọlọpa ba tete ṣe paramu. ki ọwọ ijoba le tẹ awọn oniji biti na lasiko yi, ni irin mi ki nto kọjasi Ibadan o

Lakotan mo bẹ Ijọba pe ki nwọn bawa tun titi Lawson ti o lọ si Itirẹ ati Mushin ti lo ọ si Itirẹ ṣe, ki awọn wolewole Mushin mejuto ọrọ koto iku ti mo sọ pe awọn ngbẹ ka kiri Itirẹ ki nwọn kọ awọn eyi jẹ eyi ojẹ ni Iganmu ki wọn kọlu ole chin iga Ọba ni Itirẹ ki nwọn gbogun ti awọn ọmọ jaguda Mushin ati awọn dẹrẹba ti nwọn ko enia sinu mọto wọn lati Mushin wa si Itirẹ bi sadini (eja inu agolo)

Inu mi yio dun bi Ijọba ko ba ko eti odi si ọrọ yi, iwaju ni ọpa ẹbiti nrese, iwaju ni ẹ o maa lọ o.

Emi Ọtẹlẹmuyẹ agbọfiriu ki yin pe o di ojumọ, ire la fi pade o lagara baba loke.

# Awọn Akẹkọ Unifasiti Ibadan Ṣe Eyẹ Fun Dokita Okpara

Ibadan :-

Irohin ko to afojuba ni ile ẹkọ giga julọ ti Unifasiti Ibadan nigbati awọn akẹkọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre fi pẹlu ijo ati ayọ ki Olotu Ipinlẹ Ila Orun ati Olori ẹgbẹ Alakukọ Dokita M. I. Okpara nigbati o de si ile ẹkọ na lati wa ṣe ibẹwo awọn akẹkọ na ni ọjọ Ọjọ'bọ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi.

Nigbati Olotu na de' awọn ọmọ akẹkọ na si ti joko si gbọngan ile ẹkọ na gbara ni awọn ọmọ akẹkọ na ri mọto Olotu na pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ni awọn akẹkọ na si ti bẹrẹsi kọ orin orişirişi ati pe bi mọto Dokita Okpara ti duro ni awọn ọmọ akẹkọ na si gbe Olotu na lati inu mọto ti nwọn gbe le ejika.



Dokita M. I. Okpara Alakoso Ipinlẹ Ila—Orun

Ninu awọn ọrọ ti Dokita Okpara ba awọn ọmọ ile ẹkọ na sọ ni pe ẹgbẹ on N C NC si ti ba ẹgbẹ Afẹnifẹre papọ fun ilọsiwaju ati idagbasoke ilẹ Naijiria Olotu na si tun sọ pe ajumọṣẹpọ awọn ẹgbẹ mejeji yio gba ilẹ wa Naijiria kuro lọwọ awọn oṣelu ti ko mu ilu toro.

Dokita Okpara si tun ṣe apejuwe ilẹ Naijiria gegebi ilẹ ti nwọn fi ogiri to nfọ kọ ati panu ti njo.


CLASSIFIED PAGE

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812, HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS"

MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS *Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**

Phone 21985, Lagos.

SEDO— PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun 'Ipara" ti awọn alera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara, ọwọ tabi ẹsẹ lihun tabi yiyun nigbakugba, Alefọ, Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adain egbo ekusẹ tabi ekusẹ tabi lepalapa, Ela tabi ara işu,Akọ, inarun ati orişirişi arun "Are" miran gbogbo





Gbiyanju lati da egbogi tiiun awọn ara Ilu Tatanb Sruaşe ti nwọn npe ni "PAYAL" wb larin ọjọ mẹta run a yio ma rohin rẹ fun awọn elomiran pelu Egbogi b a yi ki şe awọn rolirobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowy egbogi arun arun ara haunhaun ti ko si şişẹ ye meji ninu eleyi si yatọ pa'apata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri igboro ati ni agbereko gqoebo pelu Orisi meji re lo wa Kekere ati Nla.

Bere egbegi Ajẹbidan SEDO PAYAL yi ni şọbu awọn PILENAB MIXTURE,

Egboigi olomi-dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹd bi ako gbonse dede ba nyo lenu bere rọ ni

WATERLOO MEDICINE STREES
FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# IROHIN IMOLE

IMỌLE ỌRE AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 713 SATURDAY JUNE 6, 1964. (2D)


## Ọga Ọlọpa Kan Wẹwọn Ọdun Mẹta

MUSHIN:- Gbogo ile ẹjọ lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun ogunlọgọ ọkẹ aimoye awọn enia ti nwọn wa si ile ẹjọ nigbati awọn ọlọpa mu ọga' ọlọpa kan, Phillip Eke wa siwaju adajọ fun ẹsun apaina ni ọjọ ọjọ *Bọ* ti iṣe ọjọ kẹran ọṣu yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran *na* ṣẹjọ s e alaye pe ọga ọlọpa ti gba isimi ifẹhinti tẹnu iṣẹ ọlọpa to ọjọ mẹta.

Ṣugbọn nigbati o lọ si oko tẹ ni Ama-Ekepe-*Ala*fia ni agbegbe *Be*nde ni ọjọ kejila osu keji ọdun ti o koja yi, ni o ba ri awọn enia meji kan ninu oko o si ta ọlọpa kan, Kalu Obegu nibọn.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia adugbo na sare de nigbati nwọn gbọ igbe "oro o" ti *ọ*lọpa na nke ninu igbo, nigbati awon enia na si de ibẹ nw*ọ*n ba ọdaran na ti o nṣe ajo ọlọpa na.

Were ni nwọn ba gbe ọlọpa na lọ ile wosan, sugbọn o ku, ọdaran na ṣe alaye pe nigbati on de oko, on ri nkan ti o nru igbẹ ṣugbọn on ko ri ohun ti nru igbẹ na, ni on ba yinbọn si i pe boya ẹranko ni, a fi igbati on gbọ igbe enia.

Adajọ na ki ọdaran ọga awọn ọlọpa naa o lọ fi ọdunrun pọnun (£3000) tan ran si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn ọdun-mẹta jura.

# ẸNITI O JI 1YAWO GBE GUN IYAWO RẸ L'ỌBẸ PA!

Yaba-: Kẹkẹ pamọ gbogbo enia lẹnu nigbati awọn ọlọpa de ọdaran kan, Karimu Ayinla ni igbekun wa siwaju adajọ Agba ile ẹjọ kekere yaba fun ẹsun apania ni ọjọ ọjọ'Bo ti iṣe ọjọ kerin oṣu yi.

Ọga awọn Ọlọpa, ọgbẹni Peter Oluwọle ti o nba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ilẹ ẹjọ pe, ọdaran na nfẹ obinrin kan, Wosilatu Adeleke ni oju ọ n a, ọrọ awọn mejeji si ti bọsi

Ṣugbọn nigbati nwọn nfẹ ara wọn fun bi ọdun kan abọ loju ọna ni Wolatu ba sere lọ ba ọdaran na nile ni alẹ ọjọ kan pe on ko ri nkan-oṣu on, o ti to bi oṣu meji pẹlu.

Ni Ọjọ na ni "wosilatu ni ko si ṣiṣe-*ko* si aiṣe, on nilati ko wa si ile Ọdaran na ni.Ṣugbọn Wosilatu ni ki on to le kọ wa sile, on gbọdọ gbaOwo ipalẹmọ.

Lẹsẹkẹsẹ ni Ọdaran na ba si apoti rẹ ti o si mu pọnun mẹjọ (£8) jade, o si fun Wosilatu pe ki o l*ọ* palẹmọ wa silẹ Wosilatu si gba Owo na *o* lọ si ile wọn.

Nigbati *yio* fi to nkan di Ọjọ marun si Ọjọ na. Wosilatu kọ gbogbo awọn ẹrun rẹ wale, awọn ẹru rẹ wale awon mejeji si jijo ngbe papọ bi Ọkọ ati iyawo.

Ṣugbọn nigbati awọn mejeji gbepọ fun igba diẹ nigba*ti* ọdaran na lọ si ibi iṣẹ ni ọjọ kan, ni ode lati ibi iṣẹ ti ko si de ba iyawo rẹ nile mọ, Wosilatu ti palẹ gbogbo ẹru rẹ mọ, o si kolọ si ibomiran.

Nigbati ọdaran yi de lati ibi iṣẹ ti ko si ba iyawo rẹ, ni o ba nwa kakiri ilu ko si Ibiti ko wa iyawo rẹ na de.

Nigbati o si ri iyawo rẹ na nibiti o ngbe iyawo na tun bere *owo* lọwọ ọdaran gbogbo owo ti ọdaran na fun Wosilatu ki e to le pada wale *owo na* le ni pọnun mẹrinl*a (£14) N*igbati owo de ọwọ Wosil*atu* o tun ko ẹru rẹ wale.

Ṣugbun nigbati *W*osilatu ti ko wa sile rẹ tan ni ojo kan ni odar*an* na ba ronu titi nigbati inu bii ti ko si mo ohunti on le ṣo mo ni o ba yọ ada si *iyawo* rẹ o *si* ṣa lada titi obinrin na fi ku sinu agbara *ẹjẹ ni ojo* kejila osu kẹta odun yi.

Nigbati adajọ gbọ ẹjọ awọn ọlọpa tan, ko tilẹ gbọ ọrọ kan lẹnu ọdaran na, ṣugbọn *oyẹ* gbi gbọ ẹjọ na siwaju.

Bi nwọn ba si ti pari ẹjọ na si ẹ o maa gbọ.


BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

*UN*

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

OWO *PỌKU* NI A *SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa we lẹẹkanṣoṣo ko ri iyatọ*


# Ipade Pajawiri Bẹrẹ

Lati Oju Ewe Kini ro pe nipa ọrọ awọn osisẹ ti nwọn da isẹ silẹ na ni nwọn fẹ sọ.

Bi nwọn ba ti pari ipade na si, ẹ o maa gbọ ninu iwe Irohin wa

Onirohin wa kan sọ pe, Alhadi Abubakar yio de si Eko ni owurọ yi, sugbọn ako le sọ bi nipa idaisẹsilẹ na ni alakoso na mbọ wa si Eko fun, ṣugbọn ti o ba de ni owurọ yi ao bi lere ẹo si ma gbọ ni ọla.

Gbogbo awọn oṣiṣẹ bọọsi Munisipa ni nwọn da iṣẹ silẹ, ti awọn oṣiṣẹ ti nwọn wa sibi iṣẹ ti nwọn ko si ṣiṣẹ ko ri Mọto wọ lọ si ile ni asiko. Awọn onitakisi ngba ṣile mẹwa lati Yaba de Eko ninu ọjọ ana.



Alhaji Adebọla


## POOLS SPECIAL

BY POOLS STARS

The following are the best draws for Fixed Odds punters this week.

| | | |
|---|---|---|
| Sydnly Aust | V | Melita |
| Hakoah | V | Polonia |
| Sunshine | V | Trident |
| Waverby | V | Helotic |
| Austria | V | Enfield |
| Croatia | V | Rangers |



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone:- 21985

Editor:- TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street, Lagos (6/6/64)